Bibeli fun awon omode

# Ileri Olorun fun Abrahamu



Akosile lati owo: Edward Hughes

Ayaworan: Byron Unger; Lazarus
Alastair Paterson

Olu'lo: M. Maillot; Tammy S.

Atunmo ede: Oluwashina Oluwadimu

Alakoso: Bible for Children
www.M1914.org

©2023 Bible for Children, Inc.
Iwe ase: Oni ase lati se atunko tabi attune itan yi,
niwon igba ti o ko so di owo.



Leyin ikun omi,
awon eniyan inu
aye se eto kan.



Won wipe “A o ko ilu nla kan pelu ile iso ti o ga de Orun.” “Je ki a maa gbe papo” Gbogbo won n so ede kan naa.


Olorun fe ki awon eniyan maa gbe kaakiri lori ile aye ti o seda. Nitori naa o se ohun nla kan. Lojiji, awon eniyan bere sii so ede ti o yato si ara won. Olorun fun won ni awon ede titun.

Awon to n so ede kan naa ko ara won jo papo si ibi kan naa. O jo wipe eru nba won lati baa won miran ti ede won ko ye ara won se papo. Nipa bayi, Olorun mu ki awon eniyan lo tedo si awon orile-ede kaakiri. Ilu ti won ti jade ni a n pe ni Babeli ti o tumo si idaru-dapo.



Leyin opolopo odun, ni ibi kan ti a n pe ni Uri ti awon ara Kaldea, Olorun ba okunrin kan soro ti oruko re n je Abramu.  Olorun paa l’ase fun un wipe “Kuro ni ile yi ki o si lo si ile kan ti emi yoo fi han o”.



Abramu gboran.  Olorun dari re si Kenaani Aya re, Sarai, ati omo arakunrin re, Loti, lo pelu re.



Ni Kenaani, Abramu ati Loti di oloro. Won ni agbo eran ti o po. Ko si si papa oko fun opo eran naa.



Awon darandaran Lotiba awon darandaran Abramu ja. Abramu ba wipe, “ma se je ki wahala ki o wa laarin wa, jeki a pinya. Loti mu ibi ti o ba wu o ninu ile naa”.



Loti yan awon ilu ati agbegbe ti o ri pe gbogbo koriko ibe tutu daradara. Ilu ati ile naa dara loju.  Sugbon o je ilu ti o buru gidi gan.



Leyin ti sLoti lo, Olorun tun ba Abramu soro. "Maa fi gbogbo ile Kenaani fun iwo ati iru omo re lailai" Abramu ati Sarai ko bimo. Bawo ni Olorun yoo se mu ileri nla Re yi se?





Awon okunrin meta to
Abramu ati Sarai wa lati odo Olorun.
Won wipe, "Oo ni omo laipe". Sarai rerin. Ko
gba oro Olorun gbo. Oje omo Aadorun odun.



Olorun so fun Abramu wipe, Abrahamu, ni
yoo maa jebayi ti Sarai yoo si maa je Sara.



Olorun tun so fun Abrahamu pe Oun Olorun yoo pa ilu buburu meji tii se Sodomu ati Gomora run. Omo arakunrin Abrahamu, Loti ati idile re, si n gbe ni Sodomu

Loti gba ikilo Olorun gbo, sugbon awon oko omo re ko lati kuro ni Sodomu. Ha, o se! Won ko gba Olorun gbo.



Loti ati awon omobinrin re mejeeji nikan ni o sa asala.  Ina ati Okuta ina bo sori ilu buburu naa.



O ba ni lokanje wipe aya
Loti se aigboran si ikilo
Olorun o si boju weyin.
O si di owon iyo.



Oluwa pa ileri re mo fun Abrahamu ati Sara. Won ni omo ni ogbologbo ojo won gege bi Olorun ti so. Ayo won kun pupo nigba ti a bi Isaaki.





Oseese ki Abrahamu tun ro nipa ileri Olorun lati fun ohun ati awon omo re ni ile Kenaani lailai. Olorun yoo pa ileri naa mo.

Olorun maa n pa ileri re mo.

# Ileri Olorun fun Abrahamu

Itan lati inu oro Olorun, Bibeli

lari ka ninu

Genesisi ori kokanla de ori kokanlelogun (11-21)

"Iwole oro re funwa ni imole."
Orin Dafidi Ori kokandinlogofa ese adoje

Opin

Itan Bibeli yii so fun wa nipa Olorun iyanu wa t'oda wa ti osi fe ki amo ohun.

Olorun mo wipe ati se ohun ibi, ti ope ni ese. Iku ni ere ese, sugbon Olorun feran re tobe ge tofi omo re kan soso, Jesu, ranse lati ku lori igi agbelebu ki osi jiya fun ese re. Jesu si pada wa si aaye osi losi ile l'orun! Bi o ba gbagbo ninu Jesu ti osi toro idariji ese re, Yi o se eyi! Yi o si wa gbe ninu re nisisiyi, iwo yio si gbe pelu re lailai.

Bi o ba gbagbo wipe otito ni eyi, so fun Olorun wipe: Jesu mi owon, Mo gbagbo wipe ire ni Olorun, o di eniyan lati ku fun ese mi, osi wa laaye sibe. Jowo wa sinu aye mi ki osi dari ese mi jimi, ki emi ki oni aye otun nisisiyi, ati ni ojo kan ki emi kole wa pelu re titi lai. Ranmilowo lati gbo tire ati lati je omo o re. Amin.

Ka Bibeli re ki osi ba Olorun soro lojumo! Johannu ori keta ese kerindinlogun.